# ỌMỌ TORI OWO KẸHIN SI OBI RẸ

Mo ki Olotu gti awon alaba şişẹ po rẹ pe ki nwon ku işẹ adakẹdajo ko ni fi ebi pa yio amin şe ẹ ko rijojo o idi ti mo fi so eyi ni pe mo lo so oro adakẹdajo ni Mushin ojo sibẹ rẹsi ni ro awon'enia kan wa nibẹ ti nwọn si bẹrẹsi ni bu adakẹdajọ pe şebi o ro rẹni nwon uso? kini şe ti ojo uen nto? ira oro bẹẹbẹ ti nwon nfi ẹnu won so ni ojo ni po şugbon mo fẹ so fun won wipe oro şoro lati so ẹnyin enia ẹ ma kiyeti ahon nyin.

## Lati Ọwọ Ọmọ Oba-Adakẹdajọ Itirẹ

Bi enikan ko ba şişẹ ninu oro on na ni pipẹ on ni o si le ko gbog bo ara ni iyanu ẹnyin orẹ adakẹdajo ẹn yin ojişẹ adakedajo mo fẹ fi ye nyin wipe enikan ko le di enikan lowo e wo waya ti nwo nta si opọ bi awon o nina ti nta ti won be gege ni awon oni phone nta waya ti wo n s besibe awon onire o apori asore magbe si tun dogbon

Nwon ngmuti wo n gbo ri panu le tabi ara ogiri iran şo an ko'e di enikeji lowo işe ti oluku'n ototo ui a ko le tori pa o fe so oro adakedajo ranşe bi enyin ba ni igbagbo enyin le duro gbo oro ninu ojo? şebi enyinma nşişe ninu ojo nigbati a bi gbe işe fun yin şe ti e ba pari re ki e ma lọ "finish and go" ẹnyin le ni ifarada lati wa ninu ojo şugbon ti o ba jẹ oro Adakedajo ẹnyin a dori kodo sare wole bi igbati Ewurẹ nsa fun ojo.

Ki a ma ba oro wa lọ okanna lo ngnu okanna omo tori owo kẹhin si obi rẹ omo iya igberaga ni owo ti omode ba ni owo lowo yio se ẹgbẹ agba şugbon so ra n toripe o nse Iku pania

Nigbati wo ba joko lati ba Ijoye jẹun kiyesi oniti o wa niwaju rẹ odigidi ki o mi şe fi obẹ l ara reni ofa bi iwọ ba şe ọkundu enia mase fi onjẹ didun rẹ nitori pe onjẹ ẹtan ni mase lila ati lọrọ sinọ kuro ninu imo ye ara rẹ iwọ o ha fi oju rẹ woo? ki yio si mọ nitori ti ọrọ a'ye bu iye apa fun ara re bi idi ti nfo ni oju orun bi ọrọ yi ko tilẹ tan ni oju rẹ sibẹ sibẹ iwọ ni lati fi gbogbo ohun asan yi silẹ lọ

Maşe jẹ onjẹ Olọju bubu ru bẹẹni ki o ma si se jẹ onjẹ didun rẹ o toripe bi o ti nsiro ni ọkan rẹ be lori ma jẹ kio si ma mu ni ọnwi fun ọ şugbọn ọkan rẹ ko pẹ lu re okele ti iwọ je ni iwọ yio pọ jade iwọ a si sọ oro iyebiye rẹ nu mase soro li eti asiwere nitori yio gan ọgbọn re mase si ala atijọ mase bọ si oko alami Baba

Nitori di eyi mo nsọ fun nyin pe a ki gbin ọpe ki a ri eso ọgede lori re ohunti a ba gbin ni a wa vio bi ile omo re kilo fun ki o ma ba tire je Imole de ki okunku parada mo ti sọ fun nyin toletele pe emi ni a ni emi ni IMỌLẸ keta ati ikẹhin kabakun fun ile Naijiria ni tori ti a gbe okuta idigbolu ikehin si arin won.

Egbe, egbe ni fun enitı oba gan ọrọ otitọ to etitọ ni no wi fun nyin enikeni ti o ba di bolu okuta na vio fọ tutu enikeni ti okuta na ba digbolu vio fọ tutu ohunti Ẹnyin nle yi ti yato si ọna Adakedajo ojişẹ lori owo kehin si ile ikehin ohun ti mo ran nyin ko ni eleyi tabi ẹnyin ti gbagbe adehun nyin şe ohunti ẹnyin ma fi silẹ lo yi ni o kan nyin lo ju tabi enia koku loju re ri? ẸSẸ MẸFA NI Bi olowo tise nku bẹ na ni ti Talaka bi Bọrokini tise nku bẹ gegẹ ni ti oba lade aiye bi iku ti npa agba be gege ni o npa omode iku ti npa npa Okunrin lo npa obinrin.

Ohun ti un ko si ni aiye yi ohun ti o nsele ti sele ri iku ki pa enia ki o ma fi nkan kan kẹwo igba miran Ẹda e ni efori lo pa mo fe fi ye nyin wipe iku ko fe ki ema da oruko on nikan igba miran nwọn ni aran lo pa igba miran nwọn ni o sun ko ji mọ nwọn a n nşe lo fi ẹsẹ kọ ti oku sibẹ Otu tu fẹrẹfẹrẹ lo şe ti o fi ku

Mo fẹ fi ye nyin pe kari nkan wi ni eleyi KOGBE-REGBE LORUKỌ IKU Tani ẹni na ti Iku ko le pa lọna ara ni Ijọba Adakeda jọ Iku ie Alakoso kan pata ki ti obi dide lati sọrọ gbo gbo Alakoso yio ku lehin ni yio ma gbọn nri nitori ipo re ga ju ti ẹni keri lọ ore oju ni iku nba esu se ni Ijoba Adakẹdajọ

Sẹ iku mọ ohunti o nşe ọfẹ ki on ma wa ri igbakeji Alakoso Ijọba Adakẹdajọ nigba miran ti nwọn ba fẹ şe ipade ni Ijọba Adakẹdajọ eyiti ẹnyin ẹda npe ni Ijoba. Ti Adakẹdajọ ba fẹ şe işẹ iyanu miran ti ko ba lọ si Ipade, iku a fi ara rẹ si ipo Alakoso otitọ ni mo wi fun nyin ko si ẹnikan ninu ipade na ti yio di re kini ohunti o nşe a fi eşu ti o nşe aşiwaju Alatako ati Alakoso ọrọ anpe, şugbọn iku ko wo oju ẹni, kankan a fi Arun eyiti işe Alakoso la'ẹ ile-işe iku

Ẹnyin Ẹda mo fẹ ki e ko ẹkọ lara iku sitoripe ẹniti o ba mọ aşiri wa, o şoro lati şẹ sii, awon Adele Ẹda tabi igbakeji Ẹda tabi iranşẹ ti o sunmọ Ẹda nwọn şoro ẹ si,

Emi ni ọrọ, otitọ ni orukọ mi o digbi diẹdiẹ titi ọjọ mẹta ẹo tun wa gbọ iyoku nipa Ojişẹ ti o tori kẹhin si Adakedajọ.



Omo Oba Adakẹdajo

### Atoto ! Arere !!

Eyi ni lati kede fun gbogbo enia gbọ pe, awon ọmọ 'ẸGBẸ IJINLE YORUBA' yio şe Ipade won ni ile ẹkọ giga 'GASKIYA COLLEGE' Herber Macaulay S.reet Yaba ni deede agogo meran irọlẹ ọjọ ọjọ 'Bọ şe ojo kedogbọn oşu yi.

ETO IPADE

Ẹniti yio ba won sọrọ ni Alagba G. D. France ohunti yio si sọrọ le lori ni 'ẸDE YORUBA'

Ẹ jọwọ e ma sai wa si ipade yi, a lero pe ẹ o tete de atipe ẹo si tun mu awọn ọrẹ nyin wa. IRE O!

ỌLADIPỌ YEMITAN

Akowe Ẹgbẹ

# Awọn Ọdẹ Ile-Ifẹ ba awọn Ọdẹ ilu Alọ fa ijọgbọn (Apa 5)

LATI ỌWỌ ẸSỌ

Bi nwọn ti nṣe nile aiye beni nwọn nṣe lorun bi awọn ọdẹ ti wa nile aiye, nwọn mbẹ li ọrun pẹlu Ọba ilu Alọ ranṣẹ lọ sọdọ Olu igbo wipe awọn ọdẹ Ile Ifẹ fẹ ba igboro ilu Alọ jẹ, ki o yara ko awọn ọdẹ ranṣẹ si on li ti wọ gba on silẹ Bi awọn ọdẹ ọrun yio ba lọ si igboro ilu Alọ awọn li o nparada di ẹranko ọdẹ gẹgẹbi kiniun Jakumọ Ẹkun Turuku Imado, Amọtẹkun, Koriko

Nigbati awọn ọdẹ ilu Alọ de ti olukuluku wọn bere gbọ ago rẹ, Ọdẹ Ile Ifẹ kan sun o si lala wipe orişirişi awọn ẹranko şi gun si awọn nwọn ko sa gbọd, fi ọrọ ara wọnşe ẹre ni ọjọ keji niawọn akọ Ẹkun su yọ ni okere ti awọn mbọ lati ba awọn ọdẹ Ile Ifẹ ja Alukele fun ogun jo sọ wipe iru ọwọ ti awọn ara ilu Alọ yi pe kililọ jọjọ o si gba ero pupọ awọn olola oju afamo lori niyagbẹ li o mbo nko da wọn duro ki a le mọ eyiti a o şe.

O tẹ ọwọ bọ apo o yọ apo alaşọ ẹtu kan o fa ẹwọn oje kan yọ o si naa silẹ gbogbo ẹranko ti o ba ti da ẹwọn na kọja yio şubulu lẹ yio si sunlọ fọnfọn bi a ko ba ka ẹwọn na kuro nilẹ ko si ohun ti o le gbe awon ẹranko na dide lẹhin eyi ni Kọko Ẹlẹwọn idẹ so wipe ki nwọn run gbogbo awon akọ Ẹkun na pata nitori pe bi o ba di ọjọ miran nwọn o wa ka wọn mọ loji ji Ọdẹ kan ti nwon npe ni Alada-nla, fa ada rẹ yọ o si faşẹ fun ada na peki osa gbogbo awon akọ ẹkun na ti asapa idi eyi ni ko jẹki Akọ Ọkun pọ to bẹ mọ

Awon ẹranko Imado tnu yọ lokere ode lati nwọn npe oruko rẹ ni Yẹhin-yẹhin s re lọ pade awọn ẹran ko Imado o si na ẹsẹ si wọn awọn ẹranko rope ki nwọn kọkọ fi eyinl pati na Bi awọn Imado ba ti di ẹhin mọ ẹsẹ ọdẹ na afara kosi nse ni ehin rẹ kan ti o fi njeran yio tẹ si ẹgbẹ eyi ti idi rẹ ti ehin Imado kọkan fi tayo gọngọ si ẹgbẹ kan bayi ni awon ode ile ife se ti nwon si se gun awon ode ilu Alọ nigbayi ni ijọgbon wa bẹrẹ nigboro ilu Alọ

Nigbati irohin kan lo ba olu igbo wipe gbogbo won ode ilu Alọ ni awọn ọdẹ tile ifẹ se ti ọşẹ ti nşe oju o binu o pe awọn iwinlẹ Eşu ku, kurukẹrẹ ẹrọigi ọrọ oke ọrọ omi, o paşẹ fun wọn wipe ki nwọn lọ gbeja awọn ọde il Alọ

Awon Eşuku lo koko bo si nwon waju ni bati nwon yo si awon odẹ ile Ifẹ loju arẹ mu won nwon si bẹrẹsi torngbo ode kan ti nwu npe ni Pẹpẹiye ki sun lo yara si ado kan osi pe ẹru atori ki o yara wa Bẹni ẹru atori ja lọ sile, ni kiawon atori na bẹrẹ işẹ lara awon Esuku, ni awon Atori ba ko pantorẹ bo won ni gbogbo won ba salo gbogbo awon odẹ ile ifẹ ba tuja.

Ọdẹ kan ti nwọn nipe ni Ogborl odo ja bi oji bi u fi ẹru aake kan yo, si fi aake idẹ kan hu a lẹnu, o ju soke o wipe işẹ ki laake şe apa ibit o ba Ika rẹ si ni iru aake na bi iwọn ẹgbẹ gbẹrun io sọ ibẹ di Ibẹlẹ ati ila awọn rẹrọ Inu igi oke kurekure gbogbo ko ribi gbe mọ ni gbogbo wọn ba nkigbe wipe akoie du ori Olori ko awodi gbe tẹmi lọ.

Lẹhin ti gbo bo ija ti rọlẹ tan, ti awọn ọdẹ Ile-Ifẹ nşe faaji lọwọ, lẹni awọn taju kan ti nwọn ri Ewele kan ti o duro li okere, o ya iten kaiakata, o si fi ọwọ tọ ibadi, awọn Ọdẹ Ile-Ifẹ nwo o wipe kini ohun ti o fẹ şe, Oju kanşoşoşo ti o ni mbẹ ni iwaju rẹ, ẹsẹ rẹ kan si gun ju ekeji lọ.

O bere si pe awọn Ọdẹ Ile-Ifẹ bayi pe, Ẹni ba le ja ko jade awọ Ẹkun la fi şe Inu bi Ọdẹ kan ti a npe ni Alapa, o le otin fun awọn Ọdẹ Ifẹ pe Alada a da ẹ fọ Ada a dare fọ, nr wọn ba wọya ija. Bi Alada ba gbe ewele na roke rodo, bi o ba la mọlẹ tohẹ ti ko le dide, bi o ba ti gbe ori soke, yio tun şe iru Ewele yi kanna ti o duro ti o si mura lati ja, yio wipe, mati lọ o ya koiti pari, iyoku digba miran.

# Itumọ Ala

Eyi ni itumọ ala awọn onibere:

Josefu Akande Ararọmi Ibadan— Şora ki o ma ba bọ sọwọ ijamba mọto, ki o si şora lati ma rin ode oru ki alajann bubiru ma ba kọlu ọ

Tinuola Shodipẹ Abẹokuta— Ohun rere kan yio to ọ lọwọ la pẹ ojo

Aki es: Iwe paara le fi ala rẹ ranşẹ si

Josefu Alala
P O Box 159
Mushin


# Ha! Kini Eyi O




OGUN A PA YANMU—YANMU
OLORI ERIN MẸTA NI

Three elephant Brand mosquito coils dara pupọ A, ni o dara ju gbogbo ogun a pa yanmuyanmu yoku lọ.

O npa yanmuyanmu ninu ile ni kiakia oorun rẹ si dara pupọ ju gbogbo ogun yanmuyanmu yoku lọ. Bakanna ni o si tun yara pa ayan ati iden.

Tete lọ ra packet ogun yanmuyanmu Three elephant Brand coils tire loni, ki o si dan wo, iwọ yio ri bi yio ti şe pa gbogbo yanmuyanmu inu ile rẹ ti iwọ ati awọn ọmọ rẹ yio si sun daradara

Ki ori daju pe ogun yanmuyanmu olori erin mẹta yi ni nwọn mu fun ọ.

Three elephant mosquito Brand coils yi wa ni şọbu ati ile itaja kakiri orilẹ ede yi.

DISTRIBUTORS

**Amos GBEYLE & BROTHERS**

34, Docemo Street, Lagos
6 & 11 Balogun Street. West
LAGOS

# APIAS RHUMATIC & DRAGES

Jẹ ojulowo lanunhanun egbogi Jamani to lagbara gidi gidi fun lwosa LAKUREGBE" to mba enia ja



Orişirişi lakuregbe ni o wa lakuregbe Ara iyan ti o mu nsan enia ninu egungun ara lakuregbe ti o mu nau enia ni ẹsẹ rotoroto ti o njẹki ẹsẹ wuwo lati ma rin Lakuregbe ti o ngbe ri erike dinwọ kori bi o ti rorun lati lo tabi ki o ma şe ayipada ẹsẹ, ara tita bi eyiti enia fi ata obẹ pa ibadi abi egugu ara wiwo, ako iba abi pipon tabi rirun.

Bi enia ko ba gbajumọ lati tọju rẹ lasiko o le so owo pa enia

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, Tinubu Square Lagos

# Enia Marun Ku Ninu Ijamba Moto!

IBADAN: — Jinnijinni dabo gbogbo enia to ngbe ni abuleko kan ti nwọn npe ni Odo Ọra lẹba Ibadan nigba ti ijamba moto kan ṣẹlẹ ni adugbo na eyiti o fi jẹpe enia marun lo nadanu ẹmi won n na ijamba moto na eyiti o fi jẹ pe ẹsẹkẹsẹ ni awọn enia na ku ninu ijamba moto to ṣẹlẹ ni oju ọna Ibadan si Ijẹbu—Ode ni ọsan gangan ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi

Gẹgẹbi Irohin to de ọwọ wa lati ọwọ oniwe irohin wa ni Ibadan ni o ti ṣe ala yepe ... na ṣẹlẹ nigbati moto Boosi kekere kan nọmba W E 975 ... lati ilu Ijẹbu Ode to si kọlu moto to nko ẹru nla kan nọmba L K 3024 eyiti awọn moto meji na si kọlu ara wọn nibi ti nwọn si ntun ọna ṣe ni oju ọna na

Irohin fi ye wa pe gẹgẹbi awon moto na ti pade ara won ni oju ona ti nwon ntunṣe lowo na ni boosi kekere na ti kolu moto nla ti nko ẹru eyiti o nbo lati ona Ibadan ti nwon d jude si nu ikoto

Gbogbo awon moto to nkoja ni oju ona na lo si nduro lati ṣe iranlowo fun awon enia to wa ninu moto na

Irohin tun fi ye wa pe ọpọlọpọ wakati ni awon enia to wa ninu nwon moto to to nkọja ni ọju ọna na fi nduro lati le ri pe awon ṣe iranlọwọ fun awon enia to wa ninu awon moto na ati pe awon enia marun la ti ku tamuba mu ti o jẹ wipe nwon fi agbara gbe won jade ninu moto na

Oniwe irohin wa fi ye ... pe awon enia to padanu ẹmi won ninu ijamba moto na na ni nwon ti gbe lo si ile iwosan lakulaku ti Adeoye, Ibadan bakanna nwon tun gbe awọn enia to fi ara gbogbe lọ si ile iwosan ti Adẹoyọ lati lọ ṣe itoju wọn

Okan ninu awon Dirẹba moto na ni a gbọ wipe ko fi ara pa ninu ijama moto na eyiti o jẹ wipe Dreba ti ṣe keji si fi ẹsẹ rẹ ti osi gbogbe sugbon nwon si ti ṣe itọju rẹ ninu ile iwo ti Adẹoyọ, Ibadan.

Gbogbo awon Dirẹba meji na ni awon olopa ti mu ti nwon si wa ni itimole awọn olopa ni Tisan won

## YE IRAWO RẸ WO

AQUARIUS (Jan 22 - Feb 20) Arẹ yio dado ọ loni ohun gbogbo ti Iwọ yio ba ṣe loni, ṣe e pẹlẹpẹlẹ, awọn ọrẹ yio se iranlowọ fun ọ pupo ṣugbọn ki o tọju ara rẹ

PISCES (Feb 21 - Mar 20) Fir ... ni ara rẹ yio le lo ni, aṣiri rẹ yio si bo lona kan, awon to nife si ni iwo yio ba pa ... ni awon iyawo rẹ yio si gbadun rẹ to, iṣẹ rẹ yio nitẹlorun ... i ọsiwaju

ARIES Mar 21 - April 20) O yẹ ki o yanju ede Koyede ... ti mbe ni le koiti buruju loni, bi ob ... le ko ara re ni ijanu, awon oga re le ko are ba o, ko nṣe ohun ti yio pe titi lo

TAURUS (April 21 - May) Ere ijje mbe fun o lisiri ṣugbon iwo kole ṣe ki oma ṣe are rin lo si ode ki osi lo le abewo awon ara re

GEMINI (May 21 June 21) Ariyanjiyan kan yio bẹ silẹ larin iwọ pẹlu ẹkikan ṣugbọn awọn ẹniti o lẹsẹ ni lẹ ni iwọ nba lọ ... wọn ni iwọ yio ti fi ara rẹ ha iru ẹniti iwo je Dupẹ lọwọ ẹnikan to gba ọ ni imọran

CANCER (June 22 July 22) Orisirisi egbogi ti o lo lo dara jọjọ iwọ yio ni itẹlọrun awọn enia yio si ma fẹran rẹ ati wipe ẹnikan yio ṣe alaisi ninu awọn olori Ijo nvin ... fi wara wa raja a

LEO July 23 Aug 22) Aisan yio de si ọ o yẹ ki o si tọju ara rẹ ẹnikan nfẹ lati ba ọ ṣọrẹ

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ire wa fun ọ lọna kan ra o si nẹ ki o lọ ki si awon ti o fẹran rẹ gbld uso lati da gbẹ nla kan silẹ Iwo yio si gbadun awon iyawo rẹ loni

LIBRA (Sept 24 Oct 23) Ara rẹ ko ni ya tobẹ loni ... itẹlọrun ohunti o ndun ... patiki ni ọrọ ọmọlabi iyen ni ki o mojuto ... ni ostiki.

SCORPIO (Oct 24 Nov 22) Bi ... oni ti le to, ko ni ... itẹlọrun fun ọ ... ati igbadun ... ni awọn ti o wa pẹlu rẹ yio ma fi ṣe ... Enikan ti iwo ko ro tẹlẹ yio ṣe ... ni ore.

SGITTARIUS (Nov 23 Dec 21) Ma ṣe fi ara silẹ fun aisan loni ṣugbon ki o ma dara, a ki o si wa ona bi ẹ o ti ṣe toju ... hun nyin ṣe.

CAPRICORN (Dec 22 Jan 21) Iwo yio ni itẹlorun gidi gidi nigbati asiri ba bo ohun kan ti o wa ninu oka re yio juṣe

# Kereo Kereo Akiyesi Pataki




Awa na le jẹri wipe Ojulowo hanuhanu Egbogi LEOPILLS awa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana pẹlu meji rẹ ko si ninu gbogbo orisirisi Egbogi ti o wa ni Ile Naijiria

A wa na njẹwọ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia tomode t'agba ni asiko yi ti nwọn fi ṣe ọrọ ati ... rin larin ara wọn nipa Egbogi Jamani olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS

Imọran awon Dokita Oyinbo ti nwọn nṣe iwadi Egbogi LEOPILLS, yi kan so wipe bi o ti lagbara to ati bo jẹ Ojulowo girikl ati atamọ tase fun "JEDIJẸDI" bi o tiwu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni nwọn si tun fi ọwọ sọya ... pe ilẹ fun gbo bo awọn ... di tabi iju, Igbẹ sise, ... ri igb nsẹ deede, inu irun ... kuggba ara wiwo, Esanri chio didun ... ati aiko riran kedere ko d ro bur ku lara, aisan Onigb meji ati orisirisi arun miran gbogbo pẹlu

"Wipe nwọn yio ri alafia ... kia kia ti nwọn nba egbogi LEOPILLS ... o tun ma tun ẹjẹ ṣe ... enia nipa sise ... ọlun.

RANTI PE ALAFIA LOGUN ORO IJAFARA SI LEWU PẸLU

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS:— Igo nla si e meji ... (6/-6 pe e Igo kekere ṣile mẹta abo (3/6) pere. Ber Ojulowo Egbogi miran fun orisirisi A ... ti e ba fẹ n Ṣọbu won:—

WATERLOO MEDICINE STORE
8, Palm Church Street Phone 22787

# EGBE ORE META KO PE MEJI NI ILU OMUPO

**Lati Owo Bayo Tiamiyu**

Ki nto ṣoro diẹ lori awọn ẹgbẹ ọrẹ mẹta ti ilu Omupọ mo ni lati ki awọn ẹgbẹ na fun akitiyan ẹgbẹ na nipa ilọsiwaju ati eto idagbasoke ti nwọn nwa si ilu wọn eyiti iṣe Omupo ni ilẹ Igbomina ati pe mo ni lati kan saara si diẹ ninu awọn ọmọ ẹgbẹ a awọn bi Ọgbẹni R. A Bakare ti iṣe akọwe ẹgbẹ na Ogbẹni Y A Giwa ti ṣe Aṃgi ẹgbẹ na, Ọgbẹni Jimọ Giwa ati awọn miran ti emi ko ranti wọn lati daruko wọn.

Nigbati mo fi oju inu wo awọn orisirisi ẹgbẹ ti mo ti nṣe alabapade rẹ lati ile Igbomina emi ko ri ẹgbẹ to dabi ẹgbe ọrẹ meta paapa julọ nipa eto ti nwọn mọ ṣe ati nipa ilọsiwaju t awọn egbe na nfi si ilu wọn,

Mo si gb awọn egbe na ni imoran ki nwọn maṣe yi wa ti nwọn nhu pada ki nwọn si ma ṣe gekebi won ti nṣe isti ma jeki irepọ ati ilọsiwajn ma wa ninu etọ egbe wọn ki o si tun ni ilọsiwaju si ju ti atehin wa io;

Mo ro pe laipe yẹ ni awọn egbe ore mera ti ilu Omupo ti nwọn wa ni ilu Eko ṣe ayeye ere alariurin kan eyiti ko si iru re ti awon egbe miran ti nwon wa ni ilu Eko lati ile Igbomina ṣe ey ti o dabi ti egbe na, Awọn egbe na si mọ eto pupo eyiti o je wipe iru eto ti awon egbe na ma nse do ni ekeji ninu ilẹ Igbomina.

Bi awon ẹgbẹ na ti nṣo gẹgẹbi irẹpọ le ṣe na miran awọn ọmọ ẹgbẹ won bakanna ni nwọn nṣe si awọn ẹgbẹ iran ni ilẹ Igbimọ eyiti awọn ẹgbẹ na tun ṣe eto rẹ de ibi ti awọn Elere tabi awọn orilẹ ti nwọn jẹ ọmọ ile Igbimọ ti nwọn ma nsere ni ilu Eko eyiti awọn egbe na ṣe ọna bi ilọsiwaju yio ṣe le wa lori ere ti awọn onilu na ma nṣe uiya ọna ti nwọn ngbe eto na gba eyiti nwon ma nṣe gegẹbi awon onilu na yio ti ṣe fi apagbaga nipa ere ṣiṣe

Nipa ọna bayi eleyi mu ki awọn onilu bayi ma ni ọna bi nwọn yio ṣe le ma ni ilọsiwaju ninu ere ti nwọn ma ṣe ati pe eleyi tun fa emi isokan larin awon Elera bayi eyiti yio jẹki awon ti ko mo ara won tele le mọ ara daada.

IMORAN

Mo si gba awon ẹgbẹ miran ni orilẹ ede Igbimo na ti nwon ko ni mo iru ti ẹgbẹ ọrẹ mẹta ki awọn ẹgbẹ yoku mnṣe eto bi itẹsiwaju yio ṣe wa ni ilu won ati pe ki awon fi ti ẹgbẹ ọrẹ met ṣe iwa hu.

Mo ro pe ni ere ti nwọn ṣe ni ojo kẹdogbon oṣu to kọja lọ si fi han pe awon ẹgbẹ na nfe ire mọ ẹgbẹ miran gegebi ara won Ninu nwon lere ti o ṣe funawon egbe na ti awon Elere meji eyiti iṣe Salau Ipọfian ati awon Elere re eyiti iṣe onilu ti a npe ni Apala., ati Baraimoh mofolornn ṣọ Ajao ati awọn Elere re ti iṣe onilu Sakara.

Awọn elere meji yi ko pe meji ni ilẹ Igbomina nipa ona ti nwọn ngba ṣe erewọ eyiti o fa irẹpọ ati iṣọkan lọwọ ni ọjọ na eyi wipe bi nwọn ti ṣe eto ere won nasi si jẹ ohunti o mu ọgbọn ati lakaoe lọwọ eyiti iṣe iṣẹwọ awọn ẹgbẹ ọrẹ mẹta.

O yẹ ki o le sọ die fun yin nipa awọn elere mejina gẹgẹbi itan diẹ ti mo rigbọ wipe awon elere meji nama si fi diẹ to yin leti ninu rẹ;

Ọgbeni Saliu Idọfian ati awọn elere rẹ eyiti iṣe apala ti itan wọn fi ye wa pe ni nkan bi ọdun kẹdogun (15yrs) ni nwon ti bẹrẹ ere wọn eyiti o jẹ wipe eni ma jila to bẹrẹ ere na tẹlẹ ṣugbọn nisisiyi awọn eleren si ti fi enia kan le eyiti o mu awọn elere nadi mẹta'o

Ninu oro ti mọ ri gbọ ni pa awọn elere na ni mo ti gbọ pe awọn elera na ti ṣe awo (record) eyiti o jẹ peo ti pọ diẹ ninu awọn ere ti nwọn tiṣe na ni ojowu obinrin ohunti owo ma da silẹ ati Adelabu apa kini ati apa keji mo ro pe ma duru diẹ nipa ti Ọgbẹni Salau ati awọn elere rẹ

Nipa ti Ọgbẹni Buraimo Moronfolu Ajao ati awọn elere rẹ eyiti iṣe sakara elere Ọgbẹni Buraimor sowon pupọ ni ilẹ Igbomina mo ni lati fun nyin ni itan awọn elere na

Ni nkan bi ọdun meji sẹhin ni awọn elere na bere ni ilu Eko awon enia ti o bẹrẹ ere na si jẹ mọkandinlogun ṣugbon awon mẹtala lo si nṣe eto akoso ere na ba yi awọn elere na si ti ma nsire ka kiri ilu Eko ati paapa julọ ni ilẹ Igbomina ati ni Ipinlẹ Iwọ Oran Naijiria.

Awọn Elere yi si pin si ona meji nigbati ija nla kan bẹ sile larin won eyiti o jẹ wipe ọgbeni karimu Ayinla ni nwọn ti jijo nsire tẹlẹ ki edeaiyede na to be sile larin won eleyi lo mu ki ọgbe ni Karimu Ayinla sinbi ere tire lo pelu awon elegbe re

Ki nto pari ọro mi mọ ni lati kan sarasi awọn iyawo egbe ore meta ilu Omupo nipa isowopo nwon ni pelu awọn ọkọ wọn nipa eto ilosiwaju egbe na nitoripe eleyi eleyi fihan ni ojo ti awọn ẹgbẹ na se ayẹyẹ ere aladnn ni ile ẹkọ ti Public School Eletu Iwase Eko ti nwọn ko basọ eyi fun enia Oluwarẹ le ro pe awọn iyawo egqe ua lo nse ayẹyẹ ere ni ọjọ na

Eleyi si je ohunti o yẹ ki awọn obinrin miran to wa sibi ere na fi kọgbọn ati pe eleyi fi kan pe iyawo rere ni awon iyawo egbe ọre meta Ilu Omupo iṣe nitoripe awọn iyawo egbe na ti fi han ni ọjọ ere alarinrin ti awon oko wọn ṣe ni ọjọ na.

Mo tun kan saara si awọn ẹgbẹ miran ni ilu Omupo ti wọn wa sibi ere na awọn bi ẹgbẹ Amuludun, Ẹgbẹ ọrẹ marun, ọrẹ mẹwa, ati awọn egqe Six Brothers, New Stars, mo tun ki awọn bi Ogbeni A.O Ajilore eyi ti adape re nje "Wẹre ni" ati ogbeni S, Ayinla. Lẹkan si mo kan saara si ẹgbẹ ọrẹ mẹta ati awon iyawo wọn ati pe mo tun gba wọn ni imọran pe ki nwọn ma mura ki nwọn maṣe wo ẹhin lori eto ti uwọn ba nṣe nipa ilọsiwaju ilu wọn.

O digba die

## Ojogbon Imo Ijinle Eko



Aworan oke yi ni ti Dokita V. I. Lenin, eniti o gba opolopo oye imo ijinle ninu eko to si tun je okan ninu awon onimojinle ati amoye

Dokita Lenin yi s' tun je okan ninu awon ti nwon jijo ja fun ominira orile ede ile Rosia ki nwon to gba ominira ni odun 1917.

